**Appointment vacant**

1. Journey M n Printer
1. Advance Printer

Apply
Modup Press
16. Bamgbose St
Lagos.

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

NOTICE

For urgent Sale!
'CROPPER' Printing Machine with Electric Motor and Starter. 3 Rollers & 2 Chases £200, or Nearest offer. We are selling it because of space for another New Machine.
Write or Call:-
Ire-de Printing Works
9, Massey Street
LAGOS.

VOL. III No. 154 MONDAY JUNY 4 — JULY 10 1960 KOBO KAN (1d)

# Ile ise alase Ijoba Apapo ile Naijiria ko imoran igbimo Asofin ilu Eko

AWỌN IWE TI NLỌ LARIN IGBIMỌ EKO ATI ILE IṢẸ ALAṢẸ IJỌBA APAPỌ FUN EKO FIHAN GBANGBA PE ỌPỌLỌPỌ OHUN TI IGBIMỌ EKO FẸ ṢE NI IJỌBA APAPỌ KO GBA PE KI WỌN ṢE.

Ile iṣẹ Alaṣẹ Ijọba ti kọ fun Igbimọ Eko pe ki oma ṣe ifowo kun owo awọn oṣiṣẹ Igbimọ eleyi ni a gbọ ninu iwe kan ti ile iṣẹ Alaṣe fi ṣọwọ si Igbimọ Eko ninu iwe yi ni a ti rika pe Igbimọ Alaṣẹ Ijọba Apapọ ko ri ohun ti o lẹ dimu ti yio fi gba imoran Igbimọ Eko pe ki o ṣe afikun owo iṣẹ awọn oga iṣẹ rẹ nida keji ẹwẹ Igbimọ Alaṣẹ Ijọba Apapọ ni awọn gba iṣẹ ti Ọgbẹni M.O. Ani eniti Ijọba ran pe ki o wo owo ti awọn oga iṣẹ ti Igbimọ Eko ngba, bi o ba yẹ ki a fi kun tabi ko yẹ, iwe na tun lọ bayi a lero pe gẹgẹbi iyan jija ti Igbimọ yin ja, ti a si ri pe o yekoro, ṣugbọn ṣibẹ awa ko ri ohunkohun ti o le mu wa ọrọ wa ti akoko pada pe aho le gba imọran kan ti o ju ti Ọgbẹni M.O. Ani ti a yan lati ṣiṣẹ ti iṣẹ rẹ ri tẹ wa lọrun.

Ṣugbọn lori ọrọ Owo ti Adajọ Mbanefo ṣe ni ẹnu lọlọ yi, ile iṣẹ Alaṣẹ Ijọba sọ wipe awọn ko ṣe kanrangbọn rara, ṣugbọn ohun ti Ọgbẹni Ani tiṣe ni awọn gba.

Adele Akọwe Igbimọ sọ ọrọ yi nigbati awọn oga iṣẹ ẹlẹgbẹ rẹ nkun sinu, oni lotọ ni pe gbogbo awọn ni ọrọ owo yi ko tẹ lọrun Ṣugbọn sibẹ kosi ohun ti awọn le'ṣe ju wipe ki awọn ma wo lọ.

Ile Iṣẹ Apapọ tun sọ wipe ki ọmọ ẹgbẹ Igbimọ Eko kan to lọ si irin ajo ni ilu okere, tabi larin Eko. wọn gbọdọ gbaṣẹ lẹnu awọn Adele Akọwe Igbimọ ni on ko ni sọ wipe ki Igbimọ gba aṣẹ yi Ijọba Apapọ tun kọ lati ya Igbimọ lowo Ṣugbọn wọn sọ wipe awọn wa lati ṣe alatilẹhin fun igbimọ ti wọn ba ri owo ya ni ibomiran. Ṣugbọn Ijọba gbọdọ faṣẹ si adehun iyawo, na.

Rogbodiya tun wa: larin igbimọ pẹlu ijọba apapọ nipa ọrọ pokiti igbimọ ni ijọba apapọ gbọdọ ma san owo fun pokiti ti awọn ngbe ni gbogbo ile iṣẹ won ṣugbọn ijọba apapọ kọ lati ṣe bẹ. Alaga igbimọ Eko ni Ijọba apapọ gba pe ki o ma gba ẹgbẹrun pọun lọdun.

## Ileke Ihamora Naijiria




ILEKE IHAMORA TI Apapọ Orilẹ Ede Naijiria ni Ọba Ilu Oyinbo ti fi aṣẹ si. Gẹgẹbi ẹti ri Aworan rẹ ami ohun ti gbogbo awọn nkan ti ẹ nri ninu aworan na n. Ihamọra:- Aworan dudu Ṣonṣo:- odo meji, Ẹiyẹ Idi pẹlu nina Isọngbe.- Ẹṣin funfun meji Ẹṣin ọrọ:- Idapọ pẹlu igbagbọ. Itumọ awọn ami na ni dudu ti ẹ ri yen wa fun ile olora Naijiria awọn funfun meji jẹ ami odo OYA ati BENUE titi wọn pinnu si, awọn Ẹṣin funfun meji yẹn duro fun Ọla ati Iyi Naijiria Ẹiyẹ idi duro fun agbara Ẹṣin ọrọ kẹ re ni gbogbo wa ngbadura rẹ. Ijọba Naijiria ni Ileke Ihamọra yi jẹ tirẹ ko si ẹniti o gbọdọ lo lai gbaṣẹ.

## Ogbeni Agbaje ni won tun yan ni Alaga Igbimo

OGBENI MOJEED AGBAJE Ẹniti awọn ẹgbẹ Mabọlajẹ ti nṣe ẹka awọn ẹgbẹ alakukọ ni ilu Ibadan sọ wipe awọn yọ kuro ninu ẹgbẹ ni a gbọ wipe wọn tun fi jẹ alaga Igbimọ Ilu Ibadan ninu ọsẹ to koja yi. Ọgbẹni Agbaje pẹlu Ọgbẹni L. A. M. Lawal ọkan ninu awọn ẹgbẹ Alakukọ tẹlẹ ri ti o fi ara mọ ọdọ Adeoye Adisa nigbati ija de larin Mabọlajẹ alakukọ ni kete ki a to di ibo ti koja yi ni wọn jimọ du ibo alaga yi Ṣugbọn ninu idibo fun ipo yi, Ọgbẹni Agbaje gbe ibo mẹrinle logota ọgbẹni L. A. B. Lawal si gba ibo mọkandinlogun.

Enia merinlelogorin ni wọn wa nibi ipade yi, ẹgbẹ alakukọ mẹtalelogbon ẹgbẹ Olọpẹ mọkandilogun ati awọn ti won yapa, lara alakukọ mejidilogun pẹlu awọn Oloye mẹtala. Ni kete ti wọn yan Agbaje ni alaga tan o sọrọ bayi wipe:

Nınu ibọ ti wọn di fun on, o fi han daju wipe ẹgbẹ ọlọpẹ wa lẹhin on ati wipe eyi ti han daju wipe ẹgbẹ ọlọpẹ nfẹ anfani fun gbogbo ilu Ibadan.

# IMOLE

ESIN ORO WA:
IMOLE DE OKUNKUN PARADA
Editorial Works & Office
16, Bangbose Strt,
Lagos
Telephone 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street.


## Oro Ariya Ominira.

OKU ADORUN ojọ gedegbe si ọjọ Ominira lati oni lọ, ṣugbọn sibẹ a ko ti ri ohun ti o le wu ni lori ti Igbimọ to nṣeto Ajọyọ Ominira ṣe. Ninu ọsan ọrọ wa ti ọjọ kẹtala oṣu tokọja, ọrọ ajọyọ ominira yi ni a sọ, sibẹsibẹ a ko ti ri ayipada tabi itẹpamọẹ ti awọn Igbimọ to nṣeto ariya ajọyọ Ominira nṣe. Ninu ọrọ iwe ti asọ ni ọjọ Kẹtala oṣu tokọja, a fi ye awọn Igbimọ nigbana pe ogorun ọjọ o le mẹwa ni o ku si Ominira, atipe lati ọjọ yẹn gan lo ti yẹ ki a tepa mọṣẹ lati owurọ ọjọ yẹn gan, ki ariya ajọyọ Ominira ba le yori si rere.

Awa ko bati gbe ẹnu le ọrọ yi, bikoṣepe adọrun ọjọ pere ni o ku si ominira atipe ọjọ pẹlu asiko ko duro de ẹnikan, gẹgẹbi ọrọ Oniwaasu ninu Bibeli. Ọpọlọpọ ohun lo yẹ ki a ṣe ti a ko ṣe, ọpọlọpọ lo dẹ ṣe ti o yẹ ki a ma dawọle. Orin iwuri Orilẹ-Ede wa pẹlu ọrọ rẹ ko wu ni lori nitoripe awọn ajoji lo kọ, lo dẹ tun kọ l'orin. Bawo ni awọn Alaṣẹ Ijọba fẹ ki a duro towọ-tọwọ nigbati won ba nkọ orin yi, awa Oniwe Irohin yi ko ti ri ilu na ti a le fi ṣe akajuwe pe nigbati o fẹ gba Ominira lọwọ Ilu ti o ti teri-rẹ-ba, ko ri ọmọ ilẹ rẹ kan ti o le kọ Orin iwuri ilẹ rẹ, ayafi awọn ọmọ ilẹ ilu ti o ti inu ilu ti o fẹ yebọ ninu oko ẹru ni idande. A fẹ ki a yi orin yi pada, kiṣe awa nikan bikoṣe gbogbo Naijiria.

Ti Asia Orilẹ-Ede wa, kosi ohun ti a ri sii ju wipe ki a fi ami kan gẹgẹbi irawọ tabi ohun imiran si arin rẹ. Asia na dara to, ṣugbọn yio tunbọ dara sii ti a ba le fi ami kan si larin ti yio fihan gbangba pe Orilẹ ede Naijiria jẹ Orilẹ-ede ayanfẹ.

Ni ipari ọrọ wa, awa fẹ mọ ohun ti awọn Igbimọ ti nṣeto ariya Ominira nṣe nitori awa ko ri iṣẹ iwunilori ti wọn nṣe lọwọlọwọ, o yẹ ki wọn le ṣe eto pari ki o to to ọjọ Kerindinlogbon oṣu Kẹsan Ọdun yi.

IYANJU FUN GBOGBO WA.

Ẹsin iwaju ni ti ẹhin nwo sare, owe Yoruba atijọ ni eleyi, kosi ohun ti a dẹ le fi sọ wipe ko jẹ otitọ nitoripe ẹsin iwaju ko'le boju wo ẹyin, ki o wa ṣi'ṣẹ ntẹle ma wo ti ẹyin sare. Ọrọ yin gan lo ba ọrọ idagbasoke ati igbadun pẹlu idẹra ti Naijiria lo. Lotọ awọn Alaṣẹ ati awọn Igbimọ kakiri Naijiria lo nkegbe pe nişe ni ni a nşişẹ ninu ọla ati ọla Kiṣe igbe wọn nikan lo jẹ ki a mọ pe iṣẹ nṣẹ wa nitori ọrọ bikoṣepe awa na mọ pe ọrọ oniyebiye kun ilẹ Naijiria.

Ohun ti awa fẹ sọrọ lori rẹ gan nipe ọna wo ni a o gba ti ao le fi mu ọrọ ati awọn iṣura ti o kuu inu ilẹ wa jade, ti a le fi lo wọn fun anfani ara wa? idahun ibere yi ni, ọna Meji ni osi silẹ fun wa,

(1.) Ninu ki a fi ọwọ ara wa hu awọn ọrọ ati iṣura yi wa soke ki a si lo wọn fun idagbasoke ati igbadun ara wa. (2.) Tabi ki awa iranlọwọ lati Ilu Okere fun mimu wọn jade. Ti a ba ni ki a ṣe ti akọkọ yio na wa ni ọpọlọpọ owo, awa kẹ rẹ ni ko ni owo lọwọ yi, ti a ba ni ki a ṣe ekeji yio so wa nu si oko ẹru ẹlẹkeji, ṣugbọn yio mu ilọsiwaju wa fun wa. Nitoṣe tombọ lagbara Edumare a o ma ṣe alaye kikun fun yin nimu ẹsin ọrọ wa.

Asiko Ominira ti de o si yẹ ki a ma gba ara wa ni iyanju gẹgẹbi Ilu wa yio ti ri ni ọjọ iwaju. Gbogbo ẹyin Onkawe wa ẹniti o ba ẹniti o ba ni ọrọ iṣiri lati ko ranṣẹ kio ma ṣe alaikọ ranṣẹ siwa.

Gbogbbo wa la jijọ ni Naijiria, gbogbo wa la ni lati lẹnu lọ'rọ rẹ. Ẹ kọwe iṣiri ti ẹ ba ni si:—
OLOTU IROHIN IMOLE
16, Bamgboṣe Street.
A o si tẹ nwọn jade.

## Owo ba Okunrin kan!

OGBENI A. A. Ajibola to nṣẹnu fun Ẹgbọ ni le Asofin ti apapọ ni ile ẹjọ giga ti Eko da ẹjọ fun pe ki o lọ san Igba Poun ogọta ati Meje fun U.T.C. fun Mọtọ ti o ra lọwọ wọn ti o si ṣadehun ati ma san owo rẹ diẹ-diẹ ni ọdun 1956.


# A O SI LAIPE YI

# Pep-Si-Cola

Fun asayan re

O TUTU. O SI TUNI-LARA

ILE ISE NLA
MUSHIN


## Borokini nki yin o.

Mo ki gbogbo ẹyin onkawe Irohin Imọlẹ. Ẹ ku ọjọ mẹta emi Borokini tun de lọsẹ yi lati ba yin sọrọ, ni ọsẹ tokọja, mo sọ fun yin diẹ ninu iwakiwa ti awọn ọmọge aiye isinsinyi nhu, sugbọn ni ọsẹ yi, ngo tun ba yin sọ ọrọ lori iwa aida ti awọn Obinrin wa nhu, tọmọde tagba wọn lo nhu iwa ibajẹ wọn lai bikita boya enia nwo wọn. Losẹ yi ngo sọrọ lori ọrọ aṣọ Ẹbi lakọkọ, ngo bere wipe kini itumọ aṣọ-Ẹbi? ekeji anfani wo ni aṣọ-Ẹbi nṣe fun awọn obinrin wa? ẹkẹta ijọ melo ni ao ṣe eleyi gba? ẹkẹrin ọjọ wo ni awọn obinrin wa yio ṣiwọ ninu dida ọkọ wọn ni gbese lori ọrọ aṣọ ẹbi? ekini, ohun ti a npe ni aṣọ ẹbi yi ti di aṣa awa yoruba wipe bi a ba fẹ gbeyawo, tabi ko ọmọ jade, afẹ ṣe oku ni tabi a fẹ ṣi ile, o fi dandan bi awọn Obinrin wa ba ra aṣọ ẹbi, ohun wo ni aṣọ ẹbi yi yio ṣe nigbati enia ngbero lati ṣe inawo nla bi ikomọ jade, ṣugbọn ti iyawo re ko fi lọkan balẹ ti o nyọ lẹnu wipe on fẹ da aṣọ ẹbi oni poun mẹrin, ti o si mọ wipe iṣẹ oṣu ni ọkọ yi nṣe iyawo ni iru iyawo bayi ko ni da oluwa rẹ ni gbese? nigbati awọn Obinrin wa ba si ra aṣọ ebi tan, wọn yio tun wipe awọn pe aṣọ wọn yio ko owo bi poun meji wọn yio lọ fi haya, aṣọ olowo iyebiye bi epo ba si ja si aṣọ yi, Ọkọ Obinrin na ko asamegun, nitori wipe ẹniti ofi aṣọ haya fun wọn ko ni gba aṣọ na pada, yio wipe afi dandan bi wọn ba san owo ti on fi ra aṣọ na fun on. Aṣọ iro, buba ati gele pẹlu iborun yi yio ma lọ bi pọun mẹdogun ọna wo ni ọkọ iru Obinrin bẹ yio gbe aṣọ na gba. Bi ko ba fẹ itiju, dandan ni ki o san owo fun alaṣọ ọna wo ni ẹni ẹlẹni ko fi ni wọ gbese?

Eyiti o buru ju lọ ni nigbati Oyinbo ba ko aṣọ tuntun bi aran, tabi lesi de, were wọn yio fun ni oruko, ni Oyinbo yio ba yara bu owo giga le lori. Ninu ọdun itunu awẹ ti o kọja yi, awọn Obinrin wa lọmọde lagba ni wọn fẹrẹ sare ku nitori aṣọ buruku kan ti wọn npe ni Ọlọrunmu Wọn ra iro rẹ kan ni pọun marun, wọn si ra buba rẹ ni pọun mẹta, iborun pọun meji lai ti si owo bata nibẹ.

WO IYOKU LOJU EWE KẸFA

# ṣile kan pere ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nibikibi nibikibi. Sile kan pere ni owo rira rẹ, koro egbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rẹ. Nisisiyi, enikeni le ni "ASPRO" ni ipamọ sowo lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kolu ọ tabi ẹbi rẹ. Mura sile.
Ra pakẹti "ASPRO" titun oni sile kan loni!

**'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO**


# IDIJE! IDIJE!

Eyi ni lati fi kede fun gbogbo oloye ati ọmọran papa ọmọ Ibilẹ Yoruba ti o mọ owe yoruba pa, a nfẹ ogun (20) owe Eniti tirẹ ba dara ju yio gba pọun kan ṣile-kan (£1 ; 1s ) Ki se owe ti o wọpọ ni a nwi o, papa eyiti o ba jẹ ijilẹ owe ni a fẹ o.

Orukọ. ____________________

Ibugbe. ____________________

____________________

Iṣe ____________________

Ojọ ori ____________________

Fi Owe tirẹ pẹlu Stamp Tọrọ (3d) ranṣẹ si:-

OLOTU IROHIN IMOLE
16, BAMGBOṢE STREET LAGOS.

## Akiyesi Pataki

Eyi ni lati fi kede fun gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ wipe, ẹnikẹni ti o ba ti kọ Owe Idije tirẹ, ti o si ti fi ranṣẹ, ti ko si fi Stamp tọrọ (3d Stamp) sinu rẹ, ki o tete kọ omiran ranṣẹ pẹlu Stamp tọrọ ki o si ge Idije sinu rẹ, nitori a ti fa ti akọkọ ya.

Fi owe tirẹ na ranṣẹ ki o le jẹ ẹbun Poun kan ṣilekan £1:1s enikeni ni o le kọ ọ, ko ba ṣe Ọ m ọ d e, Agba, Onile, Alejo, ko buru. Idije yi yio pari ni ipari oṣu yi lagbara Ọlọrun.

Olotu

## Gbanjo Gbanjo O ma nlo

A O BẸRẸ SI ta ọja gbanjo wa lati ipari oṣu ti o .yi (June 15—July 10th 1960) a fi eyi kede si awọn Onibara wa wipe ki Olukuluku wa ra ọja tirẹ ki a to ye ta gbanjo wa.

APEJUWE ILE ITAWE WA

Ti o ba fẹ ba wa ra ọja, wọ Bus Oshodi ki o sọkalẹ ni "Mushin Bus Stop" ti o ba si sọkalẹ tan bere Wey Street, ti o ba si nba Wey Street lọ titi o fi pin ti o ba si de opin rẹ bere 6, Ojo Road, O d u a b ọ r ẹ Mushin, Ọgba lapalapa ni odi Ojo Rd. loju, biri ti o ba ti yi si ẹhin ọgba lapa na ni iwọ yio ri Ojo Road.

AWỌN ỌJA KOṢEMANI GBANJO

Turari ẹyọnu a w ọ n Agba ati Itaja—Aṣẹṣẹ tun ja ọgbọn turari yi ni, o le lo fun Adura tetedamilohun, Arisiki Onkapọ awọn Ajẹ bi oba nlo bi ati ṣapejuwe rẹ oko ni mọ aita ọja, agbana ko si ni wọnu igba rẹ, turari ti a nta nisisiyi lagbara ni ilọpo meji ju eyiti ati nta ri lọ gbiyanju lati raa ki o si le bọ lọwọ Babalawo m'ẹran wa m'agutan wa, Iye owo rẹ 10/6d Idaji pangolo 5/6d Idanwo 3s.

IWE ILANA IFA, IYANRIN TITẸ, ETUTU ṢIṢE, IWOSAN ATI EGBOGI AJẸBIDAN

Awọn Agba ati Aiye ha ndamu rẹ bi? Awọn Babalawo ati Adahunṣe ha ti gb'ẹran aṣọ itẹlẹ ati owo rẹ bi? Agbana ati aita ọja ha kọlu ọ bi? Abiku ha nyọ lẹnu bi? Tete yara ra ọkan ninu iwe yi nitoripe Ogbokangi Babalawo ni o ṣe iwe, agbara iwaṣẹ ti awọn Babanla wa fi nṣe Akin nbẹ nibẹ.

Ti o ba nlo iwe yi gẹgẹbi ati ṣapejuwe rẹ ọwọ Araiye ko ni kao, ohunkohun ti o ba si dawọtẹ rere ni yio ma fasi.

IYE OWO 10/6d POSTAGE 1/- Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm ajẹbidan 3/ Gbedegbẹyọ Hausa 2/6d Lilo ati agbara Psalm (Iṣegun Ajẹ) pẹlu Turari 2/ Itumọ ala ati ayẹwo Ifa 3/ Fi owo ranṣẹ tabi ki o wa ra l ọ d ọ J. O. Shoyinka 6, Ojo Road Oduabọrẹ Mushin.

# Bismilai Rahamoni-Raheem Nipa Islam.

Lati ọwọ ALUFA HUSAEN MUHAMMD
10A, Thomas Street, Lagos

## Ise Aji (Apa kejo)

Iwọn nkan bi ọsẹ mẹjọ ni afi juwe iṣẹ aji kinikin ati lẹsẹsẹ fun anfani awọn onkawe Irohib Imọlẹ asi dupẹ fun Ọlọrun ti ofi iṣẹ na rọ wa lọrun ati fun awọn Olotu Irohin Imọlẹ olokiki fun gbigbawa laye Oluwa ko fi ?ibukan si iṣẹ wọn. Lẹhin ti awọn Alihaji na ti wa de ninisinyi, oku lati ba wọn sọ ọrọ iṣiti diẹ ni wọn ba, ki wọn maṣe gbagbe ohun ti wọn fi oju ri gbogbo ni wahala ati ipọnju ki wọn maṣe wa fi ra wọn silẹ fun afẹ aiye, janba, jibiti ati ṣina, titi, ijokijo eyi ti ole, ba orukọ ati ọwọ ara wọn jẹ lọ osi le mu wọn pa adanu ohun ti wọn ti ri ni iada lati ilẹ mimọ na wa.

Asi dupẹ lọwọ Ọlọrun fun mimọ awọn Alihaji wa gbogbo dari ni alafia, oju ti awọn munafiki ti wọn nro pe nkankan mbẹ ni Mọka tin pa gbogbo wọn. Ninu ẹgbẹrun mẹtala (13000) enia ti oti ilẹ na nihin lọ, ogun (20) pere loku. Asi gbọ wipe larin oṣu marun ọdun yi ti ati lo kọja iye awọn enia ti oku ni Eko nikan jẹ (1557) ẹgbẹrun kan ọgọrun marun ati ẹyọ mẹtadilọgọrun. Eyi si ja ọgọrun mẹta ati medogun oku ni arin oṣu kọkan (315). Iyẹn ni awọn ti ko tilẹ lọ si idalẹ kankan rara. Ki ni owa fa ariwo ti Mọkao.?

Afẹ ki awọn ọnisọkusọ wọn yi (papa ki ri jo) mu ẹnu wọn dani ki wọn si mọ daju pe ọrọ ibajẹ wọn ko le di Islam lọwọ ati ma dagba soke lojojumọ ki awọn imale si mu ọkan wọn gidi, ki wọn m a ṣ e fa sẹhin rara. Ni odun tonbọ ki atun ri pe ilopo ti ọdun ni ni yio lọ jẹ ipe Ọlọrun wọn fun ṣiṣe Aji.

Aki awọn ara Oro lapapọ ku idele Alihaji Sulaeman Akọṣile ati papa julọ Ẹgbẹ Masharud-Deen Society, ki Oluwa rowọ iru eyi fun wọn amin. Asi tun ki wọn amojuba ti awọn ẹni ọwọ Alihaji Tafusiri Kuranga ati Mukadamu Isa. Ki Oluwa ba wa fi iṣọ rẹ wọn kio si fi ori rere ti wẹn ran awa na, amin.

A tun dupẹ lọdọ Ọlọrun fun idari ni alafia ti ẹni ọwọ Bolaji Akewukewe ati arọwasi rẹ ati nipaki julọ Alihaji Yakubu Moṣhọbalaje (Adabiya) ati Alihaji wọn Sayidat Falila, ki Oluwa jẹ ki ari wọn pẹ ki oma ba alafia ati Aji won jẹ ki esi fi alubarika ti wọn na ran wa. amin. Awọn Alihaji ti de o, abanijẹ ẹku ọfọ.

# HALEYLLUYAH

ỌRỌ MIMỌ
INU BIBELI

## Nipa Oro Kristi

Lati ọwọ:- E. A. AWOṢIGA, Chief Lecturer Christ Universal Crusaders' Church Lagos.

Ẹ jọwọ ẹgba mi laiye lati fi esi fun diẹ ninu awọn isọkusọ ti alufa kan ti a npe ni Husaen Muhammad ma nsọ ninu iwe yin Olokiki lọṣẹ. Oyẹ ki Alufa yi ka Bibeli kio si ri pe oye on delẹ dada kioto ma sọ ọrọ lori rẹ. Ni ọjọ kan ni Alufa yi sọ ninu awọn ọrọ rẹ pe awọn Christian na tabi mu ki irun gẹgẹ bi awọn imọlẹ osi inu ẹri wa wipe bẹ na ni wọn ki irun ninu Bibeli: mo fe ki Alufa yi mọ pe atoripodi ni on nka Bibeli ko si le mọ ijinlẹ rẹ rara.

Gẹgẹ bi igbagbọ ti awa Christian, ko si eto ti o fi ara jọ irun kiki ninu awọn ẹkọ ti Jesu kiristi fi kọ wa rara. Bi oba wo Luku 11:1-4 no ri wipe Jesu ni ki a ma gba adura ba yi Baba wa tinbẹ ni ọrun ọwọ ni orukọ rẹ ki Ijọba de ifẹ tirẹ ni ki a ṣe ni aiye gẹgẹ bi ti ọrun, fun wa ni onjẹ ojọ wa loni, dari ẹṣẹ wa jin wa bi ati n dari ẹṣẹ jin awọn ti o ṣẹ wa, ma fa wa si inu idanwo tirẹ lailai amin.

Eyi fi han gbangba wipe eyi ti Alufa nwi yẹn kiṣe ti awa Christian rara. Nitori na ki ẹkilọ fun Alufa yi ki o lọ wo iwe rẹ jinlẹ dada kio to ma sọ ọrọ si ita, bi bẹ kọ gbogbo agbajọ Christian ni yio pe ni ẹjọ fun ibani ni orukọ jẹ. yio si dara bi oba le gbade wa gbangba pẹlu lati le jọ se alaye papa ẹsẹ pipọ Ọlọrun, Oluwa ko ran yin lọwọ amin.

## Ogbeni F. A. abiodun so omo loruko

Ni dede agogo mẹrin irọlẹ ni ọjọ ọsẹ ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu k ẹ f a ọdun yi 19/6/60 ninu ojo nlanla ero ya lọ lati lọ sọ ọmọdebirin jojolo ti Ọlọrun fi ta ọgbẹni F. A. Abiodun ti iṣe Olotu ile iṣẹ Ekundayọ Brother lọre pelu iyawo rẹ Omidan Abiọla Abiodun.

Alufa Asidikini J. Olumide Lucas ni o ṣe eto isin isọmọ lorukọ wọn fun ọmọdebirin na ni Ọmọtọla Aderonkẹ Wuraọla. Awọn onigbọwọ ọmọ na ni L.A. Otusanya, Iyaafin Emily Banjoko ati Iyaafin Ruth Ogundipe.

Baba ati Iya ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn ti o wa si bi ariya na lọrun titi di ọganjọ oru.

# Imura ati eye nlala ni Afin Oba Obinrin Gesi



Aworan ti ẹ nwo loke yi ti o fi aṣọ olowo iyebiye ṣe ara rẹ lọṣọ daradara yi ni arabinrin P. Sosanya ti o lọ si ilu oyinbo lati ilẹ N a i j iria. Ni agbala Ọba ilu Oyinbo nigbati o lọ si ibi ase nla kan ni agbala yi.

Iya Ọba binrin Ilu Oyinbo Ọba binrin na ati ọ k ọ rẹ iyekan wọn Princess Alexandra ni wọn se ase yi ti wọn si nfi inu didun ọ p ọ l ọ p ọ enia ti wọn wa lati gbogbo orilẹ ede agbaiye. Titi kan awọn alakoso oriṣiriṣi ilẹ kakiri agbaiye

